# OBA GESI ATI OKO RE NI OKE-OYA




AWOGBA Omode fun Giri, Eyi, Hiluk-ehin, Orere. Ra Tire Ni Ile Egbogi — ISE — Olodumare Okebola, Ibadan. 116, Great Bridge St., LAGOS



# ELETI OFE

A-NJU WON KO SE WI L'EJO



U. T. C.
SERVES
YOU
WELL



VOL. VIII No. 453. ELETI - OFE LAGOS, SATURDAY, FEBRUARY 4, 1956. KOBO MEJI (2d.)


## Oba Gesi Ati Oko Re Ni Oke-Oya

Ni ojo Alaruba (Wednesday) ose yi, ti ise ojo kini osu February 1956, ni Alaiyeluwa oba obinrin ilu Oyinbo Gesi de Kaduna ti ise olu-ilu awon omo alahusa.

Irohin so wipe awon to gun esin ti nwon to l'eba otun ati osi oju titi lati ibudo oko ofurufu, ti won si wo aso Funfun pupa, ati aso alawo ofefe ti gbogbo won nki oba k'abo. Pabambari iran wi-wo mbe lohun,

Bi oba ba kuro ni Kaduna n' yio lo si Enugu lati Enugu ni yio ta atare koja silu Ibinni lati ilu Ibinni ni yio pada wa si Eko

Lehin ti oba ba pada de si Eko ni awon omo ilewe yio se ere ti won fun oba na ri s'oju, Alayeluwa yio tun wo oko Reluwe lo si ilu Ibadan, yio de Abeokuta lohun ni awon Yoruba ati awon ilu Iwo-orun yio se eye to 'o tai ye fun oba ati oko re.

Nigbati Oba ba tun dari pada si Eko ti irin re yi, ni awa ara Eko pelu ase Oba wa, Kabiyesi Adeniji Adele Keji, ni oa fi ere eyo Adamuorisa pari gbogbo aseye na ni ojo ti Oba yio fi ilu wa sile.


*TO CLEAR*
*Gents Suede Court Shoe*
*Brown, Black & Grey*
*Before 50/- Now 42/6d*
Obtainable at :-
A. B. AKINYEMI
*104, Moloney Bridge St.,*
LAGOS.



THE NATIONAL BANK
Of Nigeria Limited.

Ona tara ti enia legba lati di onisowo nile Nigeria wa, ni ile ifowopamosi ti NATIONAL BANK Enikeni ti o ba fe, kan ogunlogo aimoye awon onisowo ile Nigeria lara, yala lati ma ta oja fun won ni, tabi lati ma ra awon ohun ogbin ile wa, ki o lo si NATIONAL BANK

ILE ISE WA NI EKO :—
37, Marina Street, P. O. Box 508, Lagos.

AWON ASOJU WA NILU OBA NIYI :—
The National Provincial Bank (Overseas Branch) 1, Princess Street, London E. C. 2.
The Comptoir National Descompte, De Par is. 8/13, King Williams Street, London E. C. 4.


## Enia Dudu Ti Won Yan Ni Atokun Oba



Aworan yi niti Ogbeni J.T. Agu'yi Ironsi ti 'o ti 'gba oye "Mejo" ninu ise Soja, on ni eni akoko to je enia dudu ti won fi se Atokun fun Alaiyeluwa Oba ilu Oyinbo Gesi.

Mejo Aguiyi-Ironsi wo ise omo-Ogun ninu odun 1942, nwon si ti si ile ise Ologun ti ilu Saro, lehin ti o se odun mefa ninu ise Ologun ti ile wa, (W.A.F.F) o s'ori're di eniti nwon yan lati lo ko ise fun ipo Oga'gun ninu ile iko'se ti a npe ni Eaton Hall, Shropshire, nilu Oyinbo, nwon si fi si ipo giga na ninu odun 1949.

Leh nna o pada wa'le, o si sise ninu ile ise Ologun ti ile wa, (West Africa) fun osu meta ni o fi se atokun fun Gomina agba Olola Sir John Macpherson, G.C.M.G. ti o ti gba isinmi pada si ilu re.

## Gomina Agba Gba Oye Nla

Alaiyeluwa Oba obinrin fi oye nla G. C. V. O. da olola nla Gomina gbogbo-gbo l'ona ni owuro ojo Alaruba (Wednesday) ki o to mu ona Oke-Oya (North) pon.

Oye yi je oye ti alaiyeluwa Oba obinrin, oloogbe Victoria da sile ni ojo kedogbon osu April, ti odun 1896, ifi dani lola fun ire rere si Oba ati awon ajole re, Oye amori o.

## Imoke Gba Ise Ojike



ENUGU— Ọlọla Dokita S.E. Imoke ti işe alabojuto işẹ ijọba Ila-orun ni nwọn gbe işẹ M.bonu Ojike fun. Dokita Imoke ni o di alaboju nawo ijọba Ila-Orun, ayc ipo işẹ ti ọlọla Ojike ti wa ki Oluwadi ẹsun owo-riba to da l'ẹbi fun aimọ ọwọ rẹ ninu owo-riba gbigba

O şi ku aye meji ti nwọn koiti fi enia si, ayc na niti awọn akọwe Alabojuto işẹ ati ti ilẹ ninu ijọba Ila-oran.

Awọn to fi aye na silẹ ni Ọgbẹni Vincent Onyeri ti işe akọwe alabojuto işẹ ati Ọgbẹni Michael Ogon ti işe akọwe alahojuto ilẹ ni Ila Orun. Awọn ni alakoso Ijọba Ila Orun (Prime Minister,) Dokita Nnamdi Azikiwe sọ wipe ki nwọn fi işẹ silẹ lẹhin iwadi ti nwọn şe.

---

Aworan yi niti Godfrey Talbot ọkan ninu awọn oşişẹ asọrọ - magbesi ẹrọ gbohun - gbohun ti o ba ọba wa silu wa. Nipa işẹ rẹ, o jẹ ẹniti nma lọ si afin ọba lorekore, fi ọlọpa ko si jẹ̀lẹ́ da duro l'ẹnu ọna.



O ti ba ọba ati ọkọ rẹ lọ silu Kanada ninu ọdun 1951, nigbana, ọba obinrin si wa bi ọmọba obinrin o si tun ba wọn rin irin ajo ninu ọdun 1953—54.

**E Ma Ka Eleti Ofe Fun Irohin Aladun**


## Enjoy Your Own —Songs—

Songs By Your Own People in the way you love masterly rendering of additional AFRICAN MUSIC :- yours, on obtainable from is

**The Association Of Nigeria Gramophone Dealers ....**
THROUGHOUT ......
..... NIGERIA ..


**Polowo oja re sinu iwe irohin eleti-ofe**


## Now Available

BUGLES, BEDSTEADS
PAINTS, DISTEMPERS,
SAFES Etc.
Just Write, Call Or
Phone 21372

**IKORODU TRADING COMPANY**

20/28 BALOGUN STREET
(P. O. BOX 395) LAGOS.
AND
NEW COURT ROAD,
IBADAN

## Kere o!

A ti ni orişirişi ogun Germany to şẹşẹ de, fun oniruru aisan tọkunrin tobinrin. Tete wa ra tirẹ k'o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**

MEDICINE STORES
7, Egerton Road, Lagos.


## Alaiyeluwa be awon omo to nkeko nilu Oyinbo wo



Aworan ti ẹ nwo, yi niti ọba obinrin nigbati on pẹlu ọkọ rẹ lọ bẹ ile ti awọn ọmọ akẹkọ ilẹ wa nghe wo ni'lu oyinbo, ile na ni a npe ni British Council's residence for Colonial Students, Haus Crescent London,

Awọn ọmọbinrin ti ilẹ wa nihin ti Alaiyeluwa mba sọrọ ni omidan Funlayọ Williams ti Eko ati omidan R Şekoni ti ilu Ibadan.

## Onitete F'orun Se 'faje

ABIDJAN—A gbọ irohin wipe Okunrin ata tẹtẹ kan ti ọpọlọpọ enia ti kilọ fun wipe tẹtẹ tita ko dara, ki o lọ ṣiwọ ninu iṣẹ buburu na ti ko gbọ ikilọ, a tilẹ gbọ wipe Ijọba ti jẹ niya nitori tẹtẹ tita yi, sibẹ ko ṣiwọ.

A gbọ wipe ni owurọ ọjọ kan ni o ṣe agbako tirẹ, nibiti o gbe nta tẹtẹ ni awọn Ọkunrin meji kan tiri nwọn si ya s'ọdọ rẹ nwọn ba ta tẹtẹ na.

Nigbati o gba owo awọn mejeji tan, ni agan ija bẹ silẹ, ki a ma fa ọrọ gun, nwọn lu pa d'ọrun ọrọ na wa n'ile ẹjọ nisisiyi.

## Ipalemo Ọba nse Ronyin Nilu Ibadan

IBADAN— Ijọba ati awọn enia Ibadan ati gbogbo ilu agbegbe ni nwọn nṣe ipalẹmọ ribiribi lati gba Alaiyeluwa Ọba Obinrin Elizabeth keji ati Ọlọla nla Ọkọ rẹ ti yio de ilu Ibadan ni ọjọ kọkanla oṣu February 1956, gẹgẹbi eto ti a ti ṣe silẹ.

Ipalẹmọ ti Ilu Ibadan pa bambari bẹni gbogbo ilu agbegbe ti o ṣe ipalẹmọ lati wa fi oju ganni Alaiyeluwa Ọba Obinrin ati Ọlọla nla ọkọ rẹ, nitoripe ohun itan ni ibẹwo awọn Alaiye na jẹ fun gbogbo enia.

A ki ẹnyin enia wa ku ipalẹmọ, ẹ si ku af'oju Sọna

## Esi Ibere

Olotu.

Inu mi yio dun ti ẹ ba le gba mi laye lati fesi si ibere Ọgbẹni Solomon Balogun alias Toff ti o jade ninu Iwe Irohin Eleti-Ọfẹ ti ọjọ 7/1/56.

Ibere na ni wipe tani agba ninu ọmọ iya mẹta, Ọgbọn, Oye ati Lakaye? Idahun ti emi ni wipe Lakaye ni agba nitoripe gbogbo ohun ti enia ba fẹ ṣe ti ko ba fi lakaye kun ko le ṣeṣe, Lakaye ni akọbi, Oye ni atẹle, Ọgbọn ni ọmọ ikẹhin wọn.

Imọ temi niyẹn o.

Emi ni

A.K. Arẹmu Ade.

Tarkwa G.C

## Owo Moto Ak'ero Fo Soke

Ni asiko ti Alaiyeluwa Ọba obinrin yi o lo ni ilu wa nihin, a gbọ wipe nipa aiko si Mọto akero nla (Bus) l'oju ọna, awọn Awa-Mọto ak'ero (Taxi-Drivers ti bẹrẹ si bu iye ti o ba wu wọn le ori ero ti o ba fẹ wọ Mọto wọn lọ si ibi ikanju.

Ohun ti a ni ero wipe o fa irufẹ iwa agadamaṣa yi wa ni wipe awọn Ọlọpa ko ri aye lati bojuto awọn awa-Mọto wọnyi, nitoripe iṣẹ wọn ti papọju ni asiko yi fun eto awọn ọpọlọpọ enia ti o fẹ fi oju ri Ọba ti nwọn nto si oju titi ilu ati ọpọlọpọ iṣẹ miran to jẹ mọ eto ti ọba wa na.

Eyi jẹ ṣẹpọn ti awọn awa-Mọto ni asiko yi, ṣugbọn a fẹ ki nwọn mọ wipe ohun ti o ntan ni Egungun ọdun ọmọ Alagbaa yio ra ọlẹlẹ jẹkọ.

## Enmo N'ilu Pota

Agbọ wipe Iyawo ọkunrin kan bi ọmọ obinrin, nigbati o di ọjọ kẹfa ti nwọn ti bi ọmọ na, ni baba ikoko - tọpẹ na sọ wipe awọn enia nfi on rẹrin nitoripe ọmọ na ko jọ on.

Ni oru ọjọ kẹfa oṣu July ọdun tokọja ni o sọ ọrọ yi ki ilẹ tomọ o ti ran ọmọ na pada lọ s'ọrun alakẹji.

Eyi jẹ enmọ ti awa ko gbọ iru rẹ ri. Ki iṣe iwa ọmọ-enia.

Idajọ kọra ni ki nwọn f'okun fun lọrun pa.


## FUN ARUN GEHIN-GEHIN

### Dan Egbogi Yi Wo



Bi arun gẹhang-hin ba nyọ o lenu lẹẹko igbati o berẹ tabi ti o nse nkan miran irora yio ma be fun oluwa rẹ bi a ba si wadi rẹ ao ri pe ohun ti o fa a mbẹ lara Kidinrin tabi Ọlọ-mu iṣẹ wọn ni lati ba gbogbo ororo ti ko dara kuro ninu ara ṣugbọn awọn Kidirin nwẹnyi ko nṣiṣẹ wọn daradara nigbamiran. Nitorina ehin ti o ndun ọ le jẹ ikilọ wipe Ọlọ mu rẹ nfẹ iranlọwọ.

Egbogi ti o daju ti o le sise yi ni DE WITT'S o nfọ idọti ara ẹni kuro o si ntu enia lara gbogbo awọn ti o ti nlo egbogi yi l'ekini aiye lo ti nrohin rẹ.

Bi iwọ ba ka diẹ ninu iwe ti awọn ti o le egbogi yi ti o nṣe iwosan fun nipa ehin didun iwọ yio mọ daju wipe bakanna ni yio ma wo arun gẹhin-gẹhin tirẹ san. Ese ti iwọ ko dan wo fun irora tirẹ boya yio jẹ ohun ti o ba o lara mu. Bere ni Sọbu ti a nta egbogi.

A ṣe egbogi DE WITT'S nipataki fun arun GẸHIN-GẸHIN IGBA-ROKO, IWORA, ARUNGUN LAKUREGBE

Idaloju wa ni wipe egbogi DE-WITT'S je eyiti o ṣe tonitoni ti ko oti kan lara rẹ.



**DE WITT'S PILLS**

for Kidney and Bladder Troubles

# MECCA PILGRIMAGE 1956

## KANO to JEDDAH

FARE £125.0.0 RETURN

PILGRIM DUES & TAXES £6.6.0

| | |
|---|---|
| Comfortable four engined D.C. 4 Skymaster Aircraft | Make your booking early at any office of WAAC or appointed agents |

WEST AFRICAN AIRWAYS CORPORATION

# ELETI QFE

A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJQ

EDITORIAL OFFICE & WORKS
28, Kosoko Street, Lagos
P. O. Box 467

CABLES & TELEGRAMS
" ELETI - QFE LAGOS "
Phone 23370

VOL VIII. NO. 453, LAGOS, SATURDAY FEB. 4, 1956.


## AWON OLOPA OBA GBARADA

T'ẹlẹgan l'oku, ni gbolohun ti o wa si ọkan wa nigbati a ṣe akiyesi iṣẹ ribiribi ti awọn ọlọpa nṣe lati igbati Alaiyeluwa, Ọba Obinrin ati ọlọla nla ọkọ rẹ, ti de si ilu wa lati ọjọ kejidinlọgbọn oṣu kini ninu ọdun 1956, yi.

Bi awọn ero to rọ wọ'lu wa ti pọ to, lati fi oju wọn ri ọba wa na, iṣẹ eto pẹlu suru ati ifarada gbogbo iyọnu awọn enia ti awọn ọlọpa ọba ṣe, ko ṣe f'ẹnu sọ. A nilati yin awọn enia to jẹ oluworan papa fun aiko ṣe aigbọnran si ọlọpa l'ẹnu, ti gbogbo nkan fi lọ dede gẹgẹbi nwọn ti ṣe eto rẹ.

Tẹlẹtẹlẹ ri, ni a ti ma nsọrọ awọn ọlọpa wipe nwọn ki iṣe iṣẹ wọn gẹgẹbi ọrẹ pẹlu awọn enia, eyiti o jẹ iṣẹ awọn ọlọpa ni awọn ilu ọlaju ti a nṣe afarawe wọn, ṣugbọn lori iṣẹ iyanu ti awọn ọlọpa ọba ṣe ni asiko ti Alaiyeluwa, ẹni-aiye-nfẹ ọba obinrinrin pẹlu ọkọ rẹ to wa bẹ wa wo nilu yi, o tọ, o si yẹ ki a kan sara iyin si wọn.

IWA RERE L'EṢO ENIA

Ohun ti a wa nfẹ ki awọn ọlọpa ilu wa mọ ni wipe gẹgẹbi nwọn ti ṣe iṣẹ wọn larin ogunlọgọ awọn enia ti ko si ikunsinu yi, kini iba ti dun to, bi wọn bale fi ifẹ ifarada ti nwọn lo na ṣe iwa ati iṣe wọn larin ilu wa lẹhin ti ọba Obinrin ati ọlọla nla ọkọ rẹ ba pada si ilu Oyinbo. Nitoripe iwa rere l'ẹṣo enia l'ode aiye.

Laiko ṣe ete l'ẹṣọ, awa sọ wipe, "Awọn Ọlọpa Gbarada Tẹlẹgan L'oku"

## Egbon Pa Aburo Nitori Aala Oko

Awọn t'ẹgbọn t'aburo meji ti wọn jẹ oniṣẹ agbẹ nilu Kalabar ni a gbọ wipe nwọn ni gbolohun asọ lori ẹnu aala oko riro wọn, baba ti o bi awọn mejeji si ṣe atunṣe ọrọ na fun wọn. Nigbati o di ọjọ keji ni aburo ikẹhin awọn mejeji sare lọ pe baba wọn ni oko tirẹ wipe gburu ni ẹjẹ nwọ lara Etim. Nigbati baba de'le, nwọn gbe lọ si'le iwosan nibiti ọjọjọ ti de ba.

K'a ma fa gun, wọn ra ẹgbọn rẹ mu ọrọ na mbẹ ni Kotu ni lọwọlọwọ yi.








Aworan inu iwe wa yi niti Alaiyeluwa aya'ba ẹ ti iṣe iya Alaiyeluwa ọba obinrin to wa bẹ wa wo nilu wa Nigeria yi.

Ẹni-ọla iya Ọba yi ni o nṣe'le de ọmọ rẹ pẹlu awọn ọmọ Ọba obinrin mejeji ti nwọn fi silẹ nilu Oyinbo; abijọ ni a fi nmọ ẹniti o ba ara wọn tan. Ẹnyin na, ẹ wo aworan yi, ki ẹ si wo Alaiyeluwa Ọba Elizabeth keji to mbẹ nilu wa yi. Kabiyesi o.

## Agba to gbin efo ika, omo re yio je nibe

(Lati ọwọ Ẹṣọ Ikoyi)

Awọn ara Eko mọni mọni lo nkọrin bayi wipe, agba to gbin ẹfọ ika, ọmọ rẹ yio jẹ nibẹ. Bayi gẹgẹ ni itan odu ifa yi lọ. Ka ka ka lawo kamika, Ka ka ka lawo kamika, Adifa fun Ọrumila, a bu fun Oriṣa, Ọrumila gbọ, o ru, o tu bọ, o si ṣetutu, Ṣugbọn Oriṣa kọ ko ru, o ṣeti gbọran si ẹbọ, o ṣe aran igbọ si eṣu.

Itan na lọ bayi wipe, igi iṣin kan mbẹ ni ẹhinkule ile Ọrumila ti o so jigbini, lojojumọ si ni awọn ọmọ Oriṣa ati awọn ọmọ Ọrumila ma nlọ du eso iṣin na ka lararọ.

Lọjọ kan, Oriṣa pe awọn ọmọ rẹ jọ, o wi fun wọn wipe, bi o ba di ọla, ki ẹnikẹni ninu wọn maṣe lọ ṣa eso isin. Nwọn si dahun pe awọn gbọ. Ki ilẹ ọjọ keji to mọ, Oriṣa ti lọ da egbogi matẹ - molẹ si idi iṣin. Nigbati ilẹ mọ awọn ọmọ Ọrumila ko le jade aisan mu gbogbo wọn, Ṣugbọn awọn ọmọ Oriṣa ko mọ iru jamba ti baba wọn ti ṣe si idi iṣin nitori awọn ọmọ Orumila, nwọn rope baba wọn ko kan fẹ ki nwọn lọ ṣa eso iṣin na mọ ni.

Gẹgẹ bi o si ti jẹ wipe nwọn fẹran eso igi yi nwọn gbẹhin yọ kẹlẹkẹlẹ lọ sidi iṣin na, nigbati nwọn tẹ egbogi yi molẹ, gbogbo wọn si di oku.

Oriṣa wa kawọ leri, o nke, o si nsọkun Ọrumila bọ sile o wẹ ṣapa-ṣapa, o wẹ ṣopo-ṣopo, o mẹkun si ẹkun igbe, o mohun sohun iyẹrẹ, o njo, o nkọrin bayi pe, Iku re lori mi o, o re, Arun re lori mi o ore, Ejọ re lori mi o o re, Ofo re lori mi o o re,

Ọrumila gbe iporun rẹ lulẹ o ri Aforan, ofu Ọkọnran osi bẹrẹ si ki bayi wipe, Kinkin Foruko kinkin Ọrumila ni Ajambete, mo ni Ajambete, o ni dasu tomola ilalẹ omi, Ojiji ko bẹru ofin ti araiye gbe silẹ nje iwọ ofulọkan ran, fo ibi fun mi loni o, ofulọkanran.

# Irohin Ilu Oyinbo

## OBA OBINRIN ELEZABETH KEJI

Lati owo Ogbeni Richard Dimbleby

Loni ẹ o gbọ ọrọ ti Ọgbẹni Dimbleby, ti ise ọjọgbọn ninu ọrọ sisọ ninu ilé ẹrọ gbohungbohun ilẹ Gẹsi sọ nipa bi wọn se gbe Ade le Ọba yi lori bii ọdun meji abọ s'ẹhin. Biotilẹjẹpe ojo rọ pupọ ni ọjọ ti o kun fun ayọ ati ariya yi, Ọgbẹni Dimbleby pẹmọ si ibiti a npe ni Westminster Abbey ni ilu London lati wo bi Ọba yi ti se fi ọwọ bọ iwe imulẹ ti o so Ade ati awọn enia rẹ pọ. Imulẹ yi ni Ọba Elizabeth fi bura wipe on yio jọba lori gbogbo enia gẹgẹbi isẹdalẹ atọwọdọwọ awọn, ati wipe on yio mu idajọ duro pẹlu anu ati gbogbo ofin Ọlọrun gẹgẹbi ilana ti o fi lelẹ.



QUEEN ELIZABETH II.

Imulẹ yi jẹ nkan ti o wuwo pupọ ṣugbọn ko mẹnu ba isẹ ilu ti yio simi le ejika Ọba, ati isẹra-ẹni ti o ni lati fihan ninu Ijọba rẹ nigbagbogbo. Eyi ko tilẹ wulo tara, nitoripe lati kekere ni wọn ti ma nkọ awọn ọmọ Alade ilẹ Gẹsi ni eto ilu, ati bi wọn nilati fi ẹmi wọn le lẹ fun isẹ ni ilẹ wọn

### GBOGBO IRETI WỌNYI NI ỌBA ELIZABETH MU ṢẸ

O ti ju ọdun meji lọ nisisiyi ti Ọba yi gba Ade, a si ri bi o se se isẹ fun awọn enia tọkantọkan, ati bi o ti gbe ireti gbogbo enia duro ninu ọrọ Keresimesi ti o so fun gbogbo aiye ni ilẹ New Zealand bi ọdun meji s'ẹhin ti o lọ bayi wipe, "Mo fẹ fihan wipe Ade ki isẹ amin yẹpẹrẹ fun ifẹwọsowọpọ wa ṣugbọn o fihan iru ẹmi ati ibatan ti o wa larin emi ati awọn enia mi.

O sore ki a to le se apejuwe ifẹ ti a ni si Ọba obinrin yi, ko se fenu sọ ni. Se nigbagbogbo ni a nri apẹrẹ ifẹ ati ọwọ Lẹhin nkan wọnyi ni a tun ni orisirisi nkan miran ti o jinle pupọ.

Gẹgẹbi isẹ Ọgbẹni Dimbleby bi ẹniti o nsọrọ lori ẹrọ gbohungbohun, o ti nba idile Ọba ilẹ Gẹsi lọ si ọpọlọpọ ajo ibẹwo, igbakugba ni isi ma sọrọ fun lati wa ọrọ ti yio fi se apejuwe ohun ti ori itẹ jẹ si orilẹ-ede, ṣugbọn nigbati a ba ranti Ọba Elizabeth keji, alafia ati agbara a sọkalẹ si ọkan wa. Bi a ba si ro lọ ti a tun pe pada, a o ri wipe ohun ti o mu ifayabalẹ ọkan yi wa ni wipe ni abẹ ijọba Ọba ti ilẹ Gẹsi ati ti awọn orilẹ-Ede ti o wa ninu ẹgbẹ Commonwealth ni ifẹhinti wa.

### NINU IPO TI O NI IGBEGA

Ti a ba sọrọ nipa ade ọba Elizabeth keji, dandan ni ka mẹnu ba ogo ti irin ajo ibẹwo rẹ ka gbogbo ilẹ Commonwealth mu ba. Alailẹgbẹ ni irin ajo yi, nitoripe ko si ikeji rẹ ninu awọn ọba isaju ti o lọ yika aiye bẹ ri. Ẹmeji ni irin ajo yi di aba nitori aisan ti o se baba rẹ, ati nigbati aisan mu wa je. Nikẹhin ti yio wa lọ ba awọn enia rẹ wọnyi, o le gẹgẹbi ọmọ alade, ati ọba obinrin ilẹ Gẹsi. Nigbati o si de ilẹ Australia nibiti o ti si ile ijọba wọn, o fi otitọ yi han ninu ọrọ rẹ ti o sọ fun wọn pe, on wa gẹgẹbi ọba obinrin wọn ati bi ọkan ninu awọn aṣelu wọn, ki si se bi ọba ti o ti ilu okere wa.

Alakoso eto ijọba Australia na ni ero yi lọkan nigbati o sọ fun ọba Elizabeth wipe ilẹ rẹ ati awọn enia rẹ ni o wa.

Ọjọ ti lọ nisisiyi ti awọn ilẹ Gẹsi yio ti imọran silẹ ti wọn yio si sọ fun awọn ilẹ ti o wa wọn labẹ lati mu se kiakia.

### OLUK ULUKU NI OMINIRA ARA RẸ.

Otitọ ti o wa nisisiyi ni wipe gbogbo ilẹ ominira ti o wa ninu ẹgbẹ Commonwealth ni o ni anfani lati se eto ijọba tiwọn, ati lati dapọ mọ ilẹ miran lai sọ fun ijọba Gesi.

Onikaluku wọn ni o ni agbara, ọrọ, ominira wọn si jẹ iwuri fun. Laika gbogbo ominira wọnyi si wọn nbọwọ fun ẹnikansoso ti o so gbogbo idile wọnyi pọ, eni na ni ọba obinrin Elizabeth keji.

Irin ajo ọba obinrin yi fi igbe aiye ilẹ miran han awọn ara ilẹ Gesi nipa irohin, aworan ati agbara ẹrọ gbohungbohun.

Nkan miran ti otun se ninu igbe aiye ọba yi ni ona ti o fi nko lala eto ijọba pọ mọ isẹ inu ile gẹgẹbi iya. Ti a ba ni anfani lati ri aworan ti o darajulọ ti ọgbẹni Annigoni fi ọwọ ya, a o ri ipa ọla ati ilẹ yi nibẹ. Nibẹ ni ọba yi joko ninu ogo ati asọ ala ti o nwo igba ti o nbọ niwaju. Gẹgẹbi ọrọ onisọna yi, wiwo rẹ nfi igbe aiye titun ti o nbọ han.

### IGBE-AIYE ỌBA OBINRIN ELIZABETH NI IFARAPAMỌ LAISI ARIWO

Ọpọlọpọ awọn oniwe ni wọn ti sọrọ ilodi ati aitọ si eyi. Otitọ idi rẹ ni wipe isẹ ti pọju fun, ti a o ba si bọwọ fun o yẹ ki a ma bu ọla fun iru asiko kekeke ti o wa fun bayi lẹkọkan ti o ba si silẹ. Awọn ọmọ rẹ mejeji ni iru ọwọ bawọnyi yẹ julọ fun. Oba Elizabeth fẹ ki awọn ọmọ rẹ mejeji ni idagbasoke gẹgẹbi awọn ọmọ miran ti ko ti idile ọba jade. Ko ju ọdun kan lọ nisisiyi ti o gbe ipinnu on ati ọkọ rẹ jade bi o se wu awọn ki awọn ọmọ wọnyi ma ni idagbasoke ninu ẹkọ pẹlu awọn ẹgbẹ wọn, ati wipe bi eyi ẹgbọn ti ise ọkunrin ba njade kiri ki wọn mu bi enia yẹpẹrẹ laisi iyọlẹnu awọn oniwe irohin ti wọn yio fẹ mọ nipa ohun ti o nlọ se. Bakana ni ifẹ wọn yi duro fun awọn ti o nkọ awọn ọmọ mejeji yi.

Ifẹ yi ni a si le se ti a ba fẹ ki ọba obinrin Elizabeth keji bori gẹgẹbi alakoso, ati gẹgẹbi iya ninu ile. Eyi ni yio si fi ami imore wa han lẹhin igbati o ti fi ọwọ bọ iwe imulẹ ti o si ti bura gẹgẹbi ọba wa.

### IRANWỌ ATI IMISI

A le pada si ọrọ ti ọlọla Winton Churchill sọ ninu ọrọ idagbere rẹ si ọba obinrin Elizabeth keji, nigbati a ba fẹ mọ ero wa. Ninu ọrọ yi, o dahun wipe "Kabiyesi, ngo fẹ ati fi ijinlẹ imore ti gbogbo awọn enia rẹ ni si ọ, ati ọlọla Ọkọ rẹ han, fun gbogbo iranlọwọ ati imisi ti a ri ni ọjọ aiye wa gbogbo, ti o ngberan ti o si ngbilẹ pẹlu agbara yika ijọba rẹ nibigbogbo". A o ranti wipe ọlọla Churchill ni o je alakoso eto ijọba ilẹ Gesi tele ki ọgbẹni Antony Eden to gba ipo rẹ lẹhinti ọgbẹni Churchill simmi.



Ẹ wo Aworan Alaiyeluwa ọba Obinrin nibi ti o nfi ọwọ pa ẹsin rẹ ni ọna lẹhin ti ẹsin na sare tan ninu ile ti nwọn nkọ ẹsin si Ọba Elizabeth keji feran ẹsin ati ere ẹsin pupọ.

## Gbangba-Teju Ti Ilu Eko




Aworan inu iwe wa yi niti awọn orișirișí aye igbadun ti wọn se si gbangba tẹju ni ọdan ti ilu Eko, (Lagos Race Course) nibiti a ti ma nsare ẹsin.

Awọn aye na jẹ orișirișí, aye ijoko awọn enia ni ajoko-gbadun itan wiwo, aye ti awọn Onimọto yio ko Mọto wọn si, aye ti awọn Oni Kẹkẹ Ologere (Bicycles) yio to kẹkẹ wọn si mbẹ l'ọtọ, ti ko ni wipe ẹnikan nse idiwọ fun ẹnikeji rẹ.

Ọpẹ gidigidi ni fun awọn alașẹ ilu wa ti nwọn pese irufẹ aye bayi fun wa lati ri Alaiyeluwa Ọba Obinrin pẹlu Ọlọla nla ọkọ rẹ ti nwọn wa fi Ọla wọn bẹ wa wo ni'lu wa. Adupẹ o.

## Asoju Iwe Irohin Eleti-Qfe be Ile-Ise wa wo



Gbukẹ ni ari Ọgbẹni Samuel L. Lalẹyẹ ti ise Asoju Iwe irohin wa nilu

Secondee, Gold Coast, ti o wa bẹ ile-ișẹ wa wo ni ọjọ Monday, ti ise ọjọ kẹtalelogun osu January, 1956.

Ọgbẹni Lalẹyẹ jẹ alakikanju enia ti o kun fun ododo ati ifẹ si ẹnikẹni, t'ọmọde-t'agba ni o si bu ọwọ fun un nitori iwa rẹ. Ọgbẹni Lalẹyẹ ti pada si Oke-okun nisisiyi.

A fi eyi ki Așoju wa wipe alafia ni ọo 'e ọhun o, ọkọ yio r'efo.

A SQ ENIA KUKURU DI GIGUN

*Bi iwo ba fe Gun bi iwon Esun Meji de Mefa. Lo Ilana Titun ti a Sese Se.*

*O DARA FUN T'okunrin-T'obinrin.*

*Ofe Ni Ao Fi fun e Kowe Si*

*ACTIVITES, (D 112)*

Kingsway, Delhi-2 India

**Plushes, Velvets, Velveteen, Damasks & Building Materials**

PLEASE CONSULT:

**Okunowo Brothers**

61, Massey Street, (Faji Market)

LAGOS, NIGERIA.

The house where Courtesy & Satisfaction are Guaranteed

## IMORAN FUN ENYIN ABIYAMO

**Enyin abiyamo e wa ra OMORELA o dara pupo fun awon omode.**

Ama je ki omode ri orun sun daradara o dara fun otutu, iko ati orisirisi arun miran ti o ma mba omode ja ni asiko ehin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe odara pupo fun awon omode

**OMORELA BABY MIXTURE**

*(SILE MEJI ABO 2/6d. FUN IGO KAN)*

O wa lọdọ :—

COMMERCIAL MEDICINE STORES

(Qualified Chemist)

10, VICTORIA STREET, LAGOS

YOUR ENGINE MAY BE MORE POWERFUL THAN YOU THINK!

I.C.A. UNLOCKS ALL THE POWER IN YOUR ENGINE

*Only*

SHELL

*has*

I.C.A

IGNITION CONTROL ADDITIVE

THE MOST POWERFUL MOTOR SPIRIT YOU CAN BUY

## Omo ogun Jamani ririn ajo mimo

Awọn ọmọ ogun Jamani bi iwọn ẹdẹgbẹta enia ti nwọn ba ọgagun Hitler lọ si ogun Biri-Hakẹm, ko ara wọn jọ. nwọn si lọ ṣe si ara, apa ibi ti ogun jija na gbe ṣẹlẹ ni iwọn ọdun mejila sehin.

Awọn enia meji ti o ṣe atọna awọn ẹdegbẹta enia na ni ọgagun General ko ening ati ọgagun Lamina. Nwọn sọ pe ko tọ ki awọn enia gbagbe ọjọ buruku eşu gbomimu na ọjọ ti Gẹsi ati Jamani fi oju ọkunrin han ara wọn

Ọpọlọpọ awọn ti enia wọn şegbe danu ninu ogun ọjọ na ko le gbagbe ọjọ na nigbati nwọn ba f'oju kan awọn agbelebu ti a fi şe isami iboji wọn ni Tọburu

Iwọ ogogi mọto Bọlugi lo ko awọn onirin ajo nwọnyi lati itẹ-oku ni Tọburuku si ibi ti oju ogun na ti şẹlẹ Bakanna ni ibẹ wa, ko yi pada si ti akoko ogun. Ha ọjọ buruku eşu gbomimu.

## Ejo Kotemilorun ti Ejemanze

Ẹjọ iku akọrin olohunyọ ti orukọ rẹ njẹ Njemanze ti nwọn şapa s'oju irin ọkọ Reluwe ni iyanọ Suru-lere ni ọjọ kẹjọ oşu April ninu ọdun tokọja, ni a gbọ wipe boya ni riro ẹjọ na ko ni duro diẹ si.

A gbọ wipe iwe ẹjọ ti nwọn ro ti adajọ fi da enia mẹfa lẹbi koi ti tẹ awọn Lọya lọwọ. Awọn enia mẹfa na ni Peter Nwangwu, Michael Adeyẹmọ Lawal Dada, Cyril Anikwe, Dada Owolabi ati Samuel Jẹgẹdẹ.

Ẹnyin ọkawe wa yio ranti wipe enia mẹrindinlogun ni wọn fi sun ẹsun apania, ti Kotu kekere fi da enia mẹjọ silẹ ki ẹjọ na to lọ Kotu Garan, ni Kotu nla nwọn tun da enia meji silẹ ki o to ku awọn mẹfa ti a darukọ wọn yẹn.

## Idaduro Kosi Fun Owo Olubadan

IBADAN. Alabẹwo işẹ Ijọba Ibilẹ Ibadan ati awọn ilu agbegbe rẹ ti kọwe si Igbimọ Ibadan wipe ipinnu ti nwọn şe lati da owo Olubadan ati awọn Oloye meji duro ko tọ suna rara. Alabẹwo ijọba (Inpector) na si sọ wipe ki Akapo-owo (Treasurer) san owo wọn Awọn Igbimọ yio da ọrọ na ro ni ipade ti nwọn yio şe ni ọjọ Satide

Owo Olubadan ati awọn agba Ijoye meieji ko gbọdọ duro o.

abọ re o.

## Ọba Obirin Si Kotu Tuntun

Ni ọjọ Tuesday ti işe ọjọ kọkanlelogun oşu January 1956, ni Aaiyeluwa Ọba obinrin lọ şi Kotu nla tuntun ti ilu Eko. Enia pọ bi omi ki asiko toto, gbogbo ijoko ti kun tẹtẹ awọn ero iworan papa ti kun ọdan rẹpẹtẹ.

Nigbati Ọba obinrin de, ki o wa wo ẹwu agbada Lọya ati fila funfun bi ẹgbọn - owu iori wọn, iyanu ni fun enia lati ri ogunlọgọ awọn ọmọ wa ti wọn jẹ Lọya wipe nwọn pọ tobẹ nilu wa nihin yi laisi awọn ti o wa ni Iwọ-orun ati Ila-orun pẹlu awọn to wa ni Oke-ọya ninu wọn.

Bi enia ko ba wo iran awọn Onişẹ Amofin ni ọjọ yi, iran oluwarẹ din ọkan.

Nigbati Ọba pẹlu ọkọ rẹ de, Gomina agba fi Adajọ agba han Ọba, oloye nla Sir Stafford-Foster - Sutton, lẹhin na ni Adajọ agba wa fi awọn Onidajọ bi Ọgbẹni Maxime-de-Commamond ti ilu Eko pẹlu Kamerun, Ademola ti Iwọ orun, Adajọ Brown ti Oke-ọya ati Ainley ti Ila-orun

Lẹhinti Ọba yẹ awọn Ọlọpa ti o to wo tan ni ọmọkunrin kekere ti orukọ Olubunmi Jibowu ti işe ọmọ bibi inu Adajọ Kotu nla ti ilu Eko, Ọgbẹni Olumuyiwa Jibowu fi itanna ilẹ wa ta Ọba obinrin na lọrẹ Lẹhin eyi ni Ọgbẹni H. O. Lucas, igbakeji Ọga işẹ Kọtu fun Ọba obinrin ni Ere fadaka kan ti a şe ni aperẹ idajọ ododo.

Bi ifẹ ti s'ọmọde t'agba ni si Ọba obinrin na ariwo nta gẹe fun Kabiyesi ni iyẹsi Ọba. KABIYESI O.



DUKE OF EDINBURGH

Eyi ni aworan ọlọla nla, Ọkọ Ọba Obinrin ti a npe ni Duke of Edinburgh, ninu aşọ oyo Ọga'gun Ologun ti a npe ni Admiral. Ọga agba ni işe ninu ọkọ Ogun ti o wa fi agba mọkanlelogun ki Alaiyeluwa k'abọ ni Ebute Eko tiwa nihin.

## Asia Ọko Ọba Obinrin



Aworan Asia ti ẹ nwo yi niti Ọlọla nla Ọkọ Ọba Obinrin ti o de si ilu wa pẹlu Alaiyeluwa Ọba Obinrin ilu Oyinbo Gẹsi. Asia yi jẹ orişirişi ọya, lati fi han gẹgẹbi o ti jẹ ọmọ ile ọba ti ilu Demark ati ila Greece, bi o si ti yin oruko ẹbi rẹ ti a npe ni "Mountbatten" ati ti Oye ọla nla rẹ gẹgẹbi Duke of Edinburgh

Orişi mẹrin ni ọya to wa ninu asia na, ti o jẹ wipe ọkọkan tọkasi igun kọkan ni ọna mẹrerin ti Oloye nla Duke of Edinburgh tan si.

Asia yi ni ao lo nigbati Oloye nla Duke of Edinburgh ba nda lọ si ibi aşeyẹ ti Alaiyeluwa Ọba Obinrin ko ba pẹlu rẹ lọ.

73/S. 2/Vol. VI/18.

# Ministry of Education Western Region

## WESTERN REGIONAL GOVERNMENT SCHOLARSHIPS

The Western Regional Government has decided to bring its scholarships awards for the year 1955/56 up to a total of 100, as advertised in Regional Gazette Notice No. 356 of 1955, by making a further 12 awards for degree courses in Agriculture and Forestry in the proportion of 8 for Agriculture and 4 for Forestry.

2. Applications are therefore invited from suitably qualified candidates of Western origin for awards tenable at the University College as well as in Colleges and Institutions abroad.

3. Suitable candidates already serving in the Agricultural or Forest Department will also be considered for awards provided they hold Grade II Cambridge School Certificates with credit in at least one science subject. All other candidates should ensure that their academic qualifications are sufficient to enable them to be placed in suitable institutions to undertake degree courses abroad, as no sholarships will be offered for pre-University training except to those candidates selected from the Agricultural and Forest Departments.

4. Application forms can be obtained direct from the Secretary to the Western Regional Scholarship Boad, Ministry of Education, Western Region, Ibadan Nigeria, or in the case of persons in the United Kingdom from the Office of the Commissioner for Western Region of Nigeria 18, Grosvenor Gardens, London SW.1.

5. Application forms must be returned direct to the Secretary to the Scholarship Board through Heads of Departments in the case of Government employees, and through Principals of Schools or Colleges or through employers as appropriate in all other cases and should be received not later than 29th February, 1956.

6. Central or Regional Ministers must not be given as referees, and applicants who resort to canvassing will be disqualified.

7. Successful candidates will be required to enter into a bond to serve the Western Regional Government for a specified period of time after the successful completion of their courses of study.

HAPPINESS SUPREME!




"Ma gives me "BANWO" and so, I'm strong, robust and healthy"

Buy BANWO for your babe
large bottle 4/6. small bottle 2/6.
Postage 1/ extra. Ask for wholesale price.
THE ABADAN STORES P.O.Box 2 18 and branches

## Won Sa Ad'emuta Pa

SHAGAMU— Enia meje ni a gbọ wipe awọn ọlọpa da duro nipa iku gbigbona ti ọkunrin ada ẹmu ta kan ti orukọ rẹ njẹ Okereke Eburu, bi ọmọ ọdun mejilelọgbọn, ara ilu Orlu nilẹ awọn Ibo, ti nwọn ṣa pa.

A gbọ wipe Eburu Ad'ẹmuta yi ngbe abule Kamalo, iwọn ibusọ mẹdogun ni abule na si ilu Shagamu ni Ijẹbu, nwọn ni lẹhinti o ti oko ẹmu rẹ de ni nwọn ri oku rẹ ninu ẹjẹ ni ọjọ Jimọ to kọja nitosi ile rẹ, a gbọ pe nwọn ṣa l'ọgbẹ ni igbaiya ati apa.

Ọrọ na wa lọwọ Ọlọpa nisisiyi.

## Ere Bolu Af'ese Gba

Awọn agbabọlu af'ẹsẹ gba ti S.C.O.A. l'Eko da awọn agba bọlu ti ọkọ ogun, ti o wa ki Ọba k'abọ ni marun laini ẹyọ kan nibi Bọlu gigba ni Ṣomolu.

Ni akọkọ bẹrẹ, awọn agba bọlu ti ọkọ ogun gbe ogun ti awọn agbabọlu ti S.C.O.A. gidigidi, ṣugbọn pẹlu gbogbo wahala wọn awọn ọmọ wa ṣe wọn bi ọṣẹ ti nṣe oju, wọn gbiyanju lati le gba ọkan wọle ṣugbọn Lawal ati Shitu ko gba fun wọn.

Lẹhin iporogan bi iṣẹju mejidinlogun, ti S.C.O.A. gba meji wọle lati ọwọ Nwaul ati Henshaw lẹhin isimi diẹ, S. C. O. A. tun ṣ'ina fun wọn, nwọn ko tile fun awọn ọmọ-ọkọ ogun laye rara. S. C. O A. tun gba ẹkẹta wọle l'ọna iyanu.

Ko pẹ lẹhin eyi ni Henshaw tun da wọn ni meji, nigbana ni ti S.C.O.A. di marun, ti Magpie di ofo (5—Nil). Wingrove wa fi ake ko'ri ko jẹ ki S.C.O.A le gba omiran wọ'le mọ ti asiko fi to.



Aworan yi nfi Moto ti Alaiyeluwa Ọba Obinrin ati ọlọla nla ọkọ rẹ wọ nilu Kaduna ni Oke Oya. Ṣerawọ gbeborọki ni ariya ere ti awọn Hausa ṣe fun Ọba.

Awọn ti o nfi ẹṣin da bira le ni Egbaa enia, ki a ma ṣẹṣẹ tun sọ ti ere alarabara to mbẹ lọwọ awọn Gambari mọ ọba obinrin papa yio ri nkan fi ṣe iranti nigbati o ba npada de Ilu Oyinbo.

## Eyie Ki Re, Ogongo Re !

KADUNA Nilu Kaduna ni Kutupu sọ nigbati Alaiyeluwa ọba obirin de ibẹ ni ọjọ Wednesday ọsẹ yi nibiti ọba ti nṣe ayẹwo awọn Ṣọja ti nwọn to lati bu ọla ati ọwọ fun u, ni Ṣọja kan ti o duro si ẹhin patapata gbe ẹiyẹ alarabara kan dani.

Eiyẹ na ni agogo-enu gigun, bi ọba ati ọkọ rẹ ti pari ayẹwo wọn tan pẹlu awọn enia ti o to ti ẹlomiran fere dabi igi, nipa diduro ṣanṣan, ni awọn wa summo enti o gbe eiyẹ na da dani, nwọn si yẹwo, pẹlu ọga awọn Ṣọja.

Awa ko mọ orukọ ti a lo pe eiyẹ na ni a ṣe sọ wipe "Eiye Kire, Ogongo Re" awọn to gbe eiyẹ na dani sọ wipe eiyẹ Burutu ni o nṣe. Ko si iru rẹ ni agbegbe wa lọtọ.

Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company, 39 Kosoko Street, Lagos.